# NIGBA TI JESU BÁ PADA BỌ̀

## 1 Tẹssalonika 4:13-18; 5:1-24

## ẸKỌ 412 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ṣugbọn nigbati nkan wọnyi ba bẹ̀rẹ si iṣẹ, njẹ ki ẹ wò òke, ki ẹ si gbé ori nyin soke; nitori idande nyin kù si dẹ̀dẹ" (Luku 21:28).**

**Ero Itunu**

Oluwa kò fẹ ki awọn ọmọ Rẹ̀ jẹ òpe nipa awọn otitọ pataki ninu Bibeli. A kà ninu 1 Tẹssalonika 4:13: "Ṣugbọn awa kò fẹ ki ẹnyin ki o jẹ òpe, ará, niti awọn ti o sùn." A sọ ọ̀rọ itunu fun wa ninu Bibeli ki a má ba banujẹ pupọ nigba ti ikú bá mú olufẹ wa kan lọ.

Awọn ti ko i ti ri igbala a maa ṣọ̀fọ wọn a si sọkún kikoro nigba ti ikú ba mu olufẹ wọn kan lọ, ṣugbọn ko ri bẹẹ pẹlu awọn Onigbagbọ́. Ikú ọrẹ tabi ọkan ninu ẹbi nitootọ a maa mu ikẹ́dun ati ibanujẹ ti o jinlẹ wá, fun Onigbagbọ́ paapaa; ṣugbọn itunu wà ninu èro yii pe bi ẹni naa bá ti ri igbala, o wà lọdọ Jesu, ati pe awa yoo tun ri i lẹẹkan si i. Bi o tilẹ jẹ pe òye rẹ̀ ko le yé wa ti nnkan wọnyii fi n ṣẹlẹ, a kò ni banujẹ "gẹgẹ bi awọn iyoku ti kò ni ireti."

Onigbagbọ́ ti a ti ipasẹ ikú pè kuro ni aiye ni ireti aaye kan ninu ọkàn rẹ̀ pe a o ji oun dide ni ọjọ kan. Nitori Jesu jinde lati inu iboji, a o ji awọn ti o gba A gbọ́ dide pẹlu. Jesu wi pe, "Emi ni ajinde, ati ìye: ẹniti o ba gbà mi gbọ́, bi o tilẹ kú, yio yè" (Johannu 11:25).

**Nigba ti Jesu Bá Dé**

Paulu Apọsteli fun wa ni apejuwe ti o yeni yekeyeke nipa bibọ̀ Jesu lati wá mu Iyawo Rẹ̀ ti o n reti Rẹ̀ lọ. Kò si aniani ninu ọ̀rọ naa pe bibọ̀ Rẹ̀ jẹ otitọ, gẹgẹ bi awọn angẹli ti sọtẹlẹ ni akoko igoke-re-ọrun Rẹ̀: "Jesu na yi, ti a gbà soke ọrun kuro lọwọ nyin, yio pada bẽ gẹgẹ bi ẹ ti ri i ti o nlọ si ọrun" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:11).

A kà a pe, "awa ti o wà lãye, ti a si kù lẹhin de atiwá Oluwa, bi o ti wu ki o ri ki yio ṣaju awọn ti o sùn." Itumọ miiran fun ọrọ yii 'di-lọwọ' ni dàdúro tabi ṣaajú. "Nitori Oluwa tikararẹ̀ yio sọkalẹ lati ọrun wá ti on ti ariwo, pẹlu ohùn olori awọn angẹli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; awọn okú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde: nigbana li a ó si gbà awa ti o wà lãye ti o si kù lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanma lati pade Oluwa li oju ọrun; bẽli awa ó si ma wà titi lai lọdọ Oluwa." Njẹ eyini ki ha i ṣe ireti ologo ati èro ti n mu ni kún fun ayọ̀?

Ṣugbọn kiki awọn ti o ti murasilẹ ni yoo gbọ́ igbe naa, ani iro ìpe naa. Gbogbo awọn eniyan iyoku ni a o fi silẹ. Ninu Luku 17:34-36, a kà nipa awọn ọkunrin meji ti yoo wà lori ibusùn, ti a o mu ọ̀kan ti a o si fi ekeji silẹ; ati awọn obinrin meji ti yoo maa lọ ọlọ pọ̀; ti a o mu ọ̀kan, ti a o si fi ekeji silẹ; ati ti eniyan meji ti yoo wà ni oko; ti a o mu ọ̀kan ti a o si fi ekeji silẹ.

Wo iru irora ti a kò le ṣalaye ti yoo jẹ́ ipin awọn ti o kù silẹ ti yoo la Ipọnju Nla nì kọja! Wò o bi o ti mu ki eniyan wariri fun ibẹ̀ru pe a le fi wa silẹ lẹyin! Ṣugbọn sibẹ bawu ki èro yii ti le bani lẹ̀ru to, a kò le fi wé ìṣẹ́ oró ti o n duro de ọkàn ti o ti ṣe alaibikita lati murasilẹ ti a o si rán nikẹyin lọ si ibi iṣẹ́ oró eyi ti Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa nipa rẹ̀ pe "iná na ki si ikú."

**Gẹgẹ bi Olè**

Apa kin-in-ni ọ̀rọ ẹ̀kọ́ wa jẹ́ fun itunu wa, ṣugbọn apa keji kún fun ikilọ. Wò bi dide Oluwa yoo ti jẹ́ ojiji tó! Gẹgẹ bi olè ni oru! Olè le rọra ṣi ferese jẹjẹ tabi ki o ṣilẹkun ki o si wọle laifi ariwo ji awọn ara ile ti o sùn. Ṣugbọn nigba ti Jesu bá dé ki i ṣe gbogbo ile ni yoo wọ̀ ṣugbọn "a o si gbà awa … soke … lati pade Oluwa li oju ọrun." Gẹgẹ bi onfà nlanlà, Jesu yoo fa awọn ti wọn ti murasilẹ sọdọ ara Rẹ̀; awọn ti o kù lẹyin yoo ri i lojiji pe Ẹni kan ti wá o si ti ji awọn "ọṣọ́" iyebiye lọ. Oluwa pe awọn ti o bẹ̀ru Rẹ̀ ti wọn si n ronú ti wọn si n sọ̀rọ nipa Rẹ̀ ni "ọṣọ́" Rẹ̀. "Nwọn o si jẹ temi ni ini kan, … li ọjọ na ti emi o dá" (Malaki 3:17).

Nigba ti a kò rò tẹlẹ, Oluwa yoo dé. Ninu Matteu ori 25, a ri apẹẹrẹ kan nibẹ nipa bibọ̀ Oluwa ninu eyi ti awọn wundia mẹwaa "tõgbé, nwọn si sùn." Ṣugbọn laaarin ọganjọ igbe ta soke pe, "Wo o, ọkọ, iyawo mbọ̀; ẹ jade lọ ipade rẹ̀."

**Awọn Amì**

Ni ọjọ kan awọn ọmọ-ẹyin Jesu bi leere: “Sọ fun wa, nigbawo ni nkan wọnyi yio ṣẹ? Kini yio si ṣe àmi wiwá rẹ, ati ti opin aiye?” (Matteu 24:3-12). Jesu wi fun wọn pe ogun, iyan, ajakalẹ-arùn, isẹlẹ, ati awọn wolii èké (tabi oniwaasu èké), ati ọpọlọpọ iwa buburu yoo pọ̀ ni ayé. Gbogbo nnkan wọnyii ni o ti ṣẹlẹ. Laaarin bi igba ọdun sẹyin si akoko ti a wà yii nṣe ni iye isẹlẹ ti o nṣẹ n pọ̀ si i.

Awọn ami miiran ti o n sọ fun wa nipa bi bibọ̀ Jesu ti sunmọtosi to ni: igberaga awọn eniyan, èké, sisọ ọ̀rọ òdi, aigbọran si obi, ojukokoro, ifẹ faaji ju ifẹ Ọlọrun lọ. Awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin ti kò ti ri igbala a maa hu ọpọlọpọ ninu irú iwa wọnyii.

**Ṣiṣọna**

“Nitorina ẹ máṣe jẹ ki a sùn, bi awọn iyoku ti nṣe; ṣugbọn ẹ jẹ ki a mã ṣọna ki a si mã wà li airekọja.” Eyi yi kò wi pe a nilati maa ṣe aisùn ni gbogbo oru ki a má si simi. Jesu n fẹ ki a jí giri nipa gẹgẹ bi wiwa ni-imurasilẹ wa ti ṣe pataki tó. Nigba ti a ba ri igbala, a nilati sọ wa si mimọ́ patapata, ki a si fi Ẹmi Mimọ́ wọ̀ wa. A mọ̀ pe buburu ni awọn ọjọ, a si nilati jigiri ki a si maa wà ni iduro gangan ninu imọ̀ otitọ wọnyii; a nilati maa ṣọna ki a maa gbadura, ki a si maa ka Ọrọ Ọlọrun lojoojumọ ki a ba le wà ni imurasilẹ. A nilati maa yẹ ọkàn wa wò lati ri i pe a kò jẹ́ ki ohunkohun yọ́ wọ inu rẹ̀ ti ki yoo jẹ ki a wà ni imurasilẹ. Ọrọ aibikita tabi iwa aibikita kan le fà wá sẹyin kuro lọdọ Oluwa.

Apa ti o kẹyin ni ori karun-un yii kún fun ọ̀rọ itọni lati ràn wá lọwọ lati wà ni imurasilẹ. Awọn ọ̀rọ itọni wọnyii ki i ṣe fun ẹlẹṣẹ bikòṣe fun awọn Onigbagbọ́. Ọrọ naa jẹ́ ti awọn “ará” -- awọn ti n reti lati pade Jesu nigba ti O bá dé. Ẹ jẹki a farabalẹ kà wọn; awọn ẹsẹ naa kúru wọn si le tete yé wa.

Paulu Apọsteli pari ọ̀rọ naa nipa sisọ bayii pe adura oun si Ọlọrun ni pe ki a pa wá mọ́ “li ailabukù ni igba wíwa Oluwa wa Jesu Kristi. Olododo li ẹniti o pè nyin, ti yio si ṣe e.” Lati wà ni “ailabukù” jẹ́ odiwọ̀n ti o ga, ṣugbọn a nilati lepa lati dé ibẹ. Peteru kọ akọsilẹ nipa awọn ti wọn n fojusọna fun bibọ̀ Jesu, o si wi pe, “Bi ẹnyin ti nreti irú nkan wọnyi, ẹ mura giri, ki a le bá nyin li alafia, li ailabawọn, ati li ailàbuku li oju rẹ̀” (2 Peteru 3:14).

**Wíwà Ni Imurasilẹ Tabi Aimurasilẹ**

Njẹ ero bibọ Jesu ha mu ayọ̀ wá sinu ọkàn rẹ bi? Bi o ti n ri awọn àmì bibọ̀ Rẹ̀ bi o ti yi ọ ká, ọkàn rẹ ha n fẹ pe ki O dé? Njẹ o ha ṣe èto ati ilepa ọjọ ti n bọ pẹlu ero bibọ̀ Kriti ninu ọkàn rẹ̀? Gbogbo eto ayé wa nilati duro lori ero yii pe, “Bi Oluwa ba fẹ” tabi, “Bi Jesu ba fà bibọ Rẹ̀ sẹyin.”

Tabi èro bibọ̀ Rẹ̀ ha n mu ẹ̀rù ati ijaya bá ọkàn rẹ? O ha nireti pe Oun ki yoo tete dé bẹẹ? Ifẹ rẹ ha n fà si awọn ohun ti ayé? Ilepa fun ọjọ ti n bọ̀ ha kún inu ọkàn rẹ tobẹẹ ti o fi n fẹ́ pé ki Jesu fa bibọ̀ Rẹ̀ sẹyin?

Oriṣi ẹgbẹ́ meji ni a ṣapejuwe rẹ̀ ninu ẹ̀kọ́ yii: awọn ọmọ imọlẹ ati awọn ọmọ òkunkun. Ẹgbẹ́ wo ni iwọ wà? Iwọ ha pẹlu awọn ti “nṣọna” tabi awọn ti “nsùn”? Ranti pé, kiki awọn ti o bá murasilẹ ni yoo gbọ́ “Ipè Ọlọrun” nigba ti O ba dé ni akoko Ipalaradà.

**AWỌN IBEERE**

1 Awọn wo ni yoo gbọ́ ariwo nigba ti Oluwa bá dé?

2 Awọn wo ni yoo kọ́ jinde lati pade Rẹ̀ ni awọsanma?

3 Ki ni itumọ ki a “sùn ninu Jesu”?

4 Bawo ni dide Jesu yoo ti jẹ́ ojiji tó?

5 Ki ni itumọ “awọn ọmọ imọlẹ”?

6 Ki ni a nilati ṣe lati wà ni imurasilẹ fun bibọ̀ Jesu?

7 Ki ni itumọ ki a “fi buburu san buburu”?

8 Ni ipari ori karun-un, ki ni ohun marun-un ti a sọ fun wa lati maa ṣe?

9 Darukọ àmì mẹjọ ti o n sọ fun wa pe bibọ̀ Kristi n sunmọ etile.